# IGBE GB'ESE OKO GB'ENMO, EYI ARA!

**Ikede**

Awa Ikede yi f u e gbegbo awon Okawe wa ati asoju wa wipe, eni keni ti owo ba seku si owo re ki o tete fi ranse ni-tori gbogbo ohun elo ti a fi nte iwe irohin lo ti gbe owo leri.
Enikeni ti ko ba fi tire ranse ao da iwe re duro ao si se aabere lati gba owo wa ni owo re. Olotu


# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO


QMQ BIBI ATI OKU
EYI NI IYE QMQ TI A BI NILU EKO NINU OSE T'O PARI NI OJQ K'J'-LA OSU AUGUST, 1955:-
QMQ BIBI JE:-317.
OKU TO KU JE-64.

VOL VII No. 429 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA AUG 20 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2d)

## OLU EPE PEGEDE

O fi gboro s'ebo; niwon ose kefa sehin ni a se irohin ti a m'enu kan ajo Igbimo oselu Ibile ti Ilu Epe ti Ijoba ngb'ero lati da sile. A so nigbana wipe Olu Epe d'araba t'apa omode koka.

Nisisiyi, oro na ti bo aso kuro lori, o si ti f'arahan gedegbe fun enikeni ri. Ninu Iwe Ikede Ijoba (Gazette) ti ojo kejidinlo-gbon osu July, 1955 to koja ni Ijoba fi Qte te wipe Olu Epe ni yio je Alakoso Ajo Igbimo Ibi-le ti Ilu Epe ti ao yan awon sa-raki enia si ni ojo karun osu September 1955.

Nje, Olu Epe pegede, o if gboro s'ebe, k'Ade pe lori, ki Bata pe lese o!



ALAIYELUWA OLU-EPE

## Igbe gb'ese Oko Gb'enmo!

Irohin aebayanu ti a ri gbo ni wipe ni Abule oko kan l'ona Idi Araba ni obinrin abileko kan ti ni owuro o fe gbe obe to wa ninu Isasun re kana, nigbati o lo si Apoti ti o gbe isasun obe si lati gbe, die loku ki ejo buje.

Enmo ki l'eyi o! aladugbo, e gba mi o! ni igbe ti obinrin na ke e rara, logan, opolopo enia ti de, nwon si pa ejo na.

Ejo ti a nwi yi gun ni Iwon ese meta, o si ni awon rusurusu.

Nje enyin okawe wa, eo ri wipe Igbe gba ese, be oko si gba enmo.

## (Esin) Allah-de Ku

EKO— Is'enia ni s'eranko, beni oro na wi. A nu se wa nigbati a gbo iku Esin ti oruko re nje Allah-De ti ise ti Qgbeni S. Ade Akodu.

Kosi eniti ko ni mo Esin na ninu awon oloworan ere esin jake-jado ile wa nihahin, nitoripe on ni olubori ninu awon Esin Isare ni gbogbo gbamgba ti awon ilu ti nwon ma nsare Esin, paapa ni Ilu Eko ati Ibadan.

O d gb'osel Allah-de


*Building for* **HIS** *future*



As trade expands jobs increase and greater opportunities will exist for your children. To serve West Africa's expanding trade The United Africa Company has invested £10,000,000 in buildings, roads, plant and equipment in the last five years. The Company builds for your child's future.

**THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LTD**

# ELETI OFE

A-NNU-WON KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS
CABLES & TELEGRAMS
25 Kosoko Street Lagos
"ELETI-OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL VII NO. 429 LAGOS
SATURDAY AUG 20 1955.


## A Ki Won Ku Ewu F'ori Jona

A gb'omopon fidi sile, kini ki Olomo se? gbolohun oke wosika wa ose yi lo jade l'enu wa nigbati a gbo irohin wipe awon kan ba ara won je nitu ipe in depo ti nwon fi se ipal ra funrawon.

Ija yi ko si se l'ori ohun meji bikose lori oro yiyan enia si Ajo apapo Igbimo nla, ti awon egbe meji ndu iat mu aye na. Eyi ko je ohun to dara rara, niwon igbati awon eniti a efe dibo fun ko je ba ara won ja, kini hat hati ti enyin alatilehin won, ti e ko je ronu wo.

Enikeni ti mo amodaju wipe Egbe Afenifere (Action Group) niti omo Yoruba, Egbe N.C.N.C ti kagbede ni ise, gbogbo awon omo Yoruba to ti sako lo, gbogbo won ni yio si pada bo wale nigbati won ba ri imole isina won.

IJA KO D'OLA

## Ole To Gbe Kakaki Nibo Ni Yio Ti Fun u

Ogboju Ole kan ni a gbo wipe o gboju gboya lati wo ogba awon Olopa (barracks) ni ile Hausa logonjo oru.

Awon ohun ti agbewiri ko ni bata, fila, Ponpo, fere, ibose ti o je ti Olopa. Nigbati nwon kigbe le ole yi, nse ni o ra pala wo baluwe, oni baluwe lo sa pamo si, sibesibe nwon ri mu.

Nje enyin okawe wa nibo ni ole yi yio ti fun kakaki ti o lo gbe.

## OKU ADELEBO L'OJU IRIN

KANO— Laipe yi ni irohin ta si wa leti pipe oko oju irin (Train) ti o mbo lati Zaria ti o fe wo ilu Kano. Nse ni oko yi ta giri nigbati o de ibikan ti awon oiye nsa odomobinrin adelebo kan fi nwon ti pa sile loju irin, ti nwon gbe ori re kuro loran re nwon si tun ge gbogbo ara re welewele sile kakiri.

Gere ti awa oko oju irin yi duro awon ti o wa ninu oko Sokale boye won mo eni na, sugbon ko, si eniti o mo, Awon ogiise inu oko oju irin fi nye wa wipe awon ro wipe oko kan sese koja nibe.

Pataperipo awon ko gbogbo ara obinrin yi sinu apo, awon si gbe lo si ilu keji fun sinsin.

Eyi n'io enyin okawe wa Talo pa adelebo yi si oju irin?


**Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti - Ofe**



## Egbogi Ti Colgate Ti A Fi Nfo Ehin Nikansoso Lo Daju Ti O Si Nmu Ireti Wa Fun Opo Enia

**LOSAN. ATI ORU KO NJEKI EHIN ENIA BAJE**

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol. Awon Alase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko nkuro beni ki nsa. Bi o ba su ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje l'osan t'oru.



Sodium N-Lauroyl Sarcosinate

SAMB RAMILIAR, PACKAGE



OKAN NINU AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.

A ti fi Ododo oro yi han ninu iwe ti awon Onisegun ehin te, awon si ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyi ti o dara fun ehin lo baje ju egbogi miran lo. Nitoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo.




Ko si egbogi ehin kan ti o dar bi eyi.
Ko ni jeki enu re run
Ko si ni jeki ehin re baje.

**O Dara T'osan T'oru Ko Njeki Ehin Enia Baje.**

## Awon Olos Begi Di Qna Efon

Qkunrin awa-moto kan ti a npe ni Salawu Akeredolu ni o mu esun wa so fun ijoba ibile Oshogbo wipe, bi on ti mbo lati ona Oke Efon, on ri awon enia kan ni petele oke na, ti nwon ko wo aso ayafi sokoto penpe ni idi won, ti gbogbo won si mu ada dani.

Nigbati on de petele oke, on ri igi ti nwon ge fi di ona, beni eru awon Oyinbo Onisowo G. B. Ollivant li o mbe ninu moto, awon eru die si mbe ninu oko ti o nlo si Ilesha ati ilu Oshogbo.

Ki on to de ibiti nwon fi igi na dubu ona on ti ya sinu popa beni on si keja ni alafia. Iberu Eyi ko jeki on le duro mo ni Ilesha titi on fi de Oshogbo.

Nigbati o pari irohin re tan, Qba ranse si Ajele, laifa oro gun, awon olopa mu awon enia meta ninu awon olosa na awon yoku salo.

Enikan ninu awon enia meta na gba wipe on jebi, Adajo ni ki o lo si ewon osu mejidilogun, ejo awon yoku si mbe nile.

## Agbako Ori Ede! Ogede Ha Le Fun Enia Lorun Bi?

L'ojo Aaruba kan, ninu osu yi, ni okunrin kogbede kan mbo wa si Eko lati ilu Ojo, o fi ese rin, a gbo lenu iyawo kogbede na wipe lati agogo marun owuro ni on pelu oko on ti bo si oju ona nitori ki nwon le tete de Eko ki orun to ta.

Ni gbogbo Abule ti nwon nkan loju ona nwon ko ri onje ra, titi nwon fi de abule Apata ni Iganmu leti Ijora: ibe ni nwon ti ri obinrin kan ti o pate ogede, nwon si ra ogede oni sisi, nitori ki o le to toko-taya je.

Gege bi ebi ti npa won to, oko ko fe ki Iyawo je ju on lo, beni iyawo ewe ko fe ki oko je ju on lo, nipa bayi, nwon nsare je ogede.

Lojiji ni ogede fun oko lorun, ni iyawo ba sare lo bu omi fun oko re, ki ni a ti imo eyi si, enia ba le je ogede ki o fun lorun ndan, Agbako ori ede, wo ni o to yi o?







## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

Medicine Store

7, Egerton Road, Lagos

## NOW, AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just write, Call, or
Phone 21372

IKORODU TRADING COMPANY

20/28, Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos,
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN


# AKIYESI

## LAGOS EXECUTIVE DEVELOPMENT BOARD

## ITIRE ROAD ESTATE

### AWON ILE IKO'LE SI FUN TITA

1. Ijoba ntun awon ile se ni Suru Lere, ti ao ma pe ni ILU QNA ITIRE, (ITIRE ROAD ESTATE) yio ni awon Opopo ona to dara, Oju agbara fun omi Ojo tabi omi aimo, omi mimu ati lilo to dara ati Ina onimonamona.
2. Awon ile na yio wa fun opolopo ile kiko ti ao ta patapata fun lilo kiko ile gbigbe si nikansoso.
3. Ijoba okede nisisiyi pe ki enikeni to ba fe, kowe wa fun iwon bi ogorun ile ikole (100 Plots) Iye owo ti ao ta ni Sile mejila-abo (12/6d) fun iwon opa Onibu-merin (Square yard) owo 50X100 fun ile ikole kan yio je bi £350. ati 40X100 fun ile ikole kan yio je bi £275.
4. Gbogbo eni ti o ba fe ra okan ninu awon ile na nilati kowe, ki o toka si Ikede yi, iba a ti kowe ri, ki o tun iwe ko.
5. Gbogbo Iwe ti enikokan bako nilati ni pon-kwun marun (£5) ninu, ao si da owo na pada fun eniti Ijoba ko ba ta ile fun u.
6. Gbogbo iwe ti enikeni ba ko ni lati lo bayi:-
   (a) Oruko enito kowe
   (b) Ibugbe Oluware, (Ako fe ibise tabi ti apoti ifiweranse)
7. Gbogbo iwe si nilati de ile ise L. E. D. B. ni Qgbon'jo osu September, 1955.
8. Enikeni ti a ba gba iwe tire ni lati ko ile ti o ya eto re (Plan) ki o fi ranse si ile ise yi, bi ijoba ba gba.
9. Awon ile miran yio tun wa fun tita ni ona Itire (Itire Road) sugbon Ijoba le yi owo won pada, ki o ma bosi iye ti a ta awon ti isiwaju.

J. W. HENDERSON
Chief Executive Officer


## Akiyesi

Enikeni Ti O Ba Nfe Ra Iwe Irohin Eleti-Qfe Nilu Tamale Ati Agbegbe Re, Kio Lo Si Qdo:-

QGBENI RAJI ALAGBE
House No. H 75. Tabi Tamale
Central Market
P.O. Box 95,
TAMALE

## Ipade Babalawo Ni Ile-Igbo

Ni ojo kejo osu June 1955, ni awon Babalawo se ipade gbogbogbo ni Ile - Igbo, Ogbeni Awotunde asoju Araba Ile - Ife ni o se alaga ojo na, oloye Araba Maka pelu awon oloye pataki lo se isongbe re.

Ogbeni G. A. Odelade, akowe Egbe Babalawo ti Oshogbo ni o ka iwe ti ipade sokoja, gbogbo won si f'aramo, O le ni irinwo enia (400) to wa si ipade na.

Ohun pataki ti nwon se ni pegebi Egbe yio ti se ni owo lowo ati akowe kan fun gbogbo Egbe Nigeria. Jije, mimu, ijo ati ayo ni awon fi pari ipade na.

Die ninu awon te wa si ipade yi ti a le daruko ni, Adisa Sonibare ti Eko, Adebowun ti Abeokuta, Akinola ati Gbadebo Dosunmu ti Ibadan pelu opolopo ti aye ko si lati daruko won.

## Eni Ti o Bimo Pada S'ogba Ewon.

**Kano** Obinrin kan ti nwon ti ju s'ewon, ni awon mu lo si Ile Iwosan, (City Hospital) nigbati o nfe bimo,

Lojo keta ti obinrin na bi omo ni awon fun da pada si ogba ewon lati lo salko re ti o ku pelu omo ojo meta lewo re

Awon enia to wa ni ile Iwosan bebe fun u, wipe ki obinrin to nse olusc alewon obinrin (Wardress) je ki o lo ojo die si, ki ara omo ikoko tape lobi le gbo die ko nwon to mu pada s'ewon. Nitoripe, awon enia ni oro wipe ogba ewon ko ni dogba pelu alafia omo na.

Oluso elewon na ni ko, o so wipe, oa ni lati mu pada lo si ogba ewon nitoripe ase ti awon pa fun on niyen, Awon enia nsokun nigbati won nmu lo, saiken ri pe ko si ewu lorun omo na, anu ese, o si lo mu okan ninu ewu fi omo re fi te lore.

## OKUNRIN KAN POKUNSO

MAIDUGURI. Irohin ti a gbo ni wipe okunrin kan ti nwon npe ni Malam Usman to nse Ise iranse (Messenger) nile ise Provincial Engineer nilu yi ni o pokunso ti nwon ba oku re ninu iyara re.

A gbo pe iyawo re to nje Binta ti ko sile, okunrin yi si lo be onidajo kekere ti kotu ibile (Alkali) ki o ba on se atunse oro na, nigbati o di ojo ti awon mejeji nilati pade ni kotu, ni nwon ko ri Malam Usman.

Nigbati nwon wa lo si ile re, oku re ni nwon ba ninu iyara.


**Chairs For Rent**

APPLY

OFE
NO. 3, AIRU STREET LAGOS



SIMENTI TI OYINBO BURHAM NI A FI KQ



ILE EGBE KUMASI TI A NPE NI PREMPEH HALL

Ninu ile yi ni awon Igbimo Ashanti Confederacy gbe nse apejo. Ile yi si je okan pataki. Sibe-sibe, Simenti Oyinbo Burhan ni a fi ko. Qpolopo ninu awon ile nla-nla ti a ko si apa Iwo Orun ile Africa, lat Iwon adorin odun sehin je eyiti a fi Simenti Burham ko. O si ti se iranlowo lorisi-risi ona fun idagba soke ilu nwonyi

Eyi fi han wipe Simenti tire lo lagbara julo ti a si je gbekele kakiri agbaiye.

**BURHAM**

PORTLAND CEMENT

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT CO. WORKS LONDON PORTLAND CEMENT

## EHIN DIDUN PẸLU IRORA



Ọna bibẹ lọwọ irora?

Njẹ iwo mo pe ọkan ninu ohun ti o nfa sababi ẹhin didun ni Kidinrin?

Bi ohunkohun ko ba ṣe Kidinrin wa awọn a ṣẹ gbogbo eri kuro ninu ẹjẹ ki gbogbo ẹya ara wa le ma ṣiṣẹ dede nigbati Kidinrin wa ba nṣe tikọti ọ, ti ko si ṣiṣẹ dede, gbogbo eri a wọjọ sinu ẹjẹ a si ma a mu ki ẹhin dun ni.

Egbogi onirodorodo fun gbigbemi ti Ọgbẹni De Witt ṣe jẹ egbogi atata a t i atamatase ti o nmu ki ẹhin dun ni salọ kiakia nipa titun ẹjẹ ṣe ati nipa mimu irora ati aisafin ba ẹnikẹni ti ẹhin didun na mba ja.

O san ki ẹniti ẹhin didun mba ja tete fi egbogi ti a nsoro rẹ yi ko loju fun ati ba le jẹ igbadun aiye jupe ki a fi dagunla ki o si ma di ẹni bẹ bẹ lọwọ lẹnu iṣẹ rẹ ati ni igbesi aiye rẹ.

Egbogi De Witt jẹ egbogi ti a ti nlo lati aiyebaiye wa, titi o fi di oni yi ko mba wiwo ẹhin didun san ti ẹgbagbeje enia ti o ti lo De Witt lo nkan sara si fun jijẹ bi idaa rẹ. Nitori idi eyi, ogunlọgọ lwc ni awọn kọ ṣowọ siwa lati fi dupẹ fun ore ribiribi ti De Witt nse fun wọn. Lọ si le tita egbogi ki o lọ ra tirẹ loni fun lilo nitori ijafara lewu.

A ṣe DE WITT'SI PILLS nipataki fun wiwo.

ẸHIN DIDUN

IRORA ORIKERIKE

LATANLATAN

IBADI SISANNI

A fọwọ sọya pe De Witt jẹ ojulowo egbogi. Gbogbo ohun elo ti a si fi ṣe e lo pe perepere ti awọn alaṣẹ ilera si kan sara si pe ko si kọlọfin kankan nipa rẹ.



# DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles


No. 73/S. 2/Vol. IV/860.

## Change in Qualifications of Candidates for Local Government Elections in the Western Region.

Attention is drawn to the amendment to section 23 of the Local Government Law effected by Law No. 18 of 1955 which comes into operation on the 11th of August.

As a result of the amendment all natives of the area of the council (male or female) who are twenty-one years of age or upwards will be qualified to be elected even if they have not paid tax.

Those who are not natives of the area also qualify provided that they have had two years continuous residence in the area and paid tax in the two Financial years preceding the date of the election, or were exempted or have paid a rate.

A native' in relation to the area of a council means a person who was born in, or whose father was born in, that area.

The qualifications of voters are not at present affected.

R.E. Brown
Acting Permanent Secretary,
Ministry of Justice and Local Government.


## IMỌRAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 3/6d. FUN IGO KAN)

O wa lodo :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

*Only Shell's patented I.C.A. gives you ALL the power of the NEW higher octane motor spirit*

# The most powerful motor spirit you can buy

SHELL
WITH
ICA
IGNITION CONTROL ADDITIVE

*Fill up and FEEL THE DIFFERENCE*

## Always Read And Advertise In Eleti Ọfẹ

# Sports To Day

## U.A.C. Vs MARINE

Last week, our sports correspondent forecast that Railway will beat P.W.D. and how was it fans. Yes it was all for Railway last week when on a wet ground they spanked P.W.D. 1-0 towards the close of the game.

Today U.A.C. and Marine will lock horn for the second round of the Challenge Cup Competition on the King George V Stadium. The winner to meet Railway. The U.A.C. have not the defence that can hold the Marine forwards of Ebe ezer, Chukwurah, Edema, Skipper Henshaw and Nkune. What of Odwyer in the goal today? will he be able to stand shots from Gedu and Baba Henshaw today? the answer is reserved.

I must again warn the defence of Rashidi, Thompson and Farinde to keep all eyes on Salvador and Ameke the two dangerous men in the U.A.C. forwardline.

We also appeal to the referee, linesmen to keep their eyes on Elijah UAC left half This is not a battle field but field of sports.

LET CALABAR SEND DOWN THE CHALLENGE CUP

Another surprise last week was the defeat of the Calabar (Holder of the Challenge Cup) by Portharcourt. They will now post the Challenge Cup to Lagos. Cheerio Sport Fans.


HAPPINESS SUPREME!




"Ma gives me "BANWO" and so, I'm strong, robust and healthy."

Buy BANWO for your babe large bottle 9/6. Small bottle 5/6 Postage 9 extra. Ask for wholesale price. THE ABADAN STORES P.O.Box 210 and branches.



HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 12 Rossborough Garden, Westminster, London, S.W.1. England


## (MARIJUANA) IGBO WO'LU IBADAN

IBADAN— A dupe lowo awon Qlopa ti nwon sa agbara ki irunbi ti ewe-taba "Soni-di-were" ti awon omo Eko nmu ti nwon npe ni "Igbo" (Indian Hemp) wole nilu Eko wa yi.

Irohin ti a ri gbo lati ilu Ibadan ni wipe kini na ti wo'lu Ibadan, ati wipe owo olopa te okunrin kan ti nwon npe ni Salawu Adisa ti nwon ri "Igbo" lowo re

Nigbati nwon de iwaju adajo Qgbeni J. A. Kester fun esun wipe nwon ri igbo ninu apoti afayo ninu Tabili re (Drawer of a Table) o so niwaju adajo wipe on ko jebi esun na, adajo fi ejo re si osu to mbo.


# AWO IKQRIN (RECORD) TI DECCA



yio mu awon orin ti o fe ati awon akorin wa sinu ile re

Lo ra won ni sobu

S. C. O. A.

A ti da Eka titun kan sile ti yio tete ma fi awon eru ti o se p taki ranse.

S. C. O. A.

Head Office:- 40 Marina Lagos

Show Room Martins/Broad Street Lagos

ATI NI

Ibadan, Sapele, Warri, Onitsha, Calabar, Aba, Port Harcourt, Kano, Enugu, Zaria & Sokoto.


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23376